# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 875 LAGOS SATURDAY JUNE 29 JULY 5 KOBO MEJI (2D) 1963


EYI ARA:

# Dokita Oyinbo Kan Ti Ran Apa Ti O Ge Lu Mora Won

BOSTON, U.S.A.-Awọn Oyiubo ọlọgbọn aiye ti tun gbe nkan ara miran de; irohin nla kan ti a gbọ lati ilu Amẹrika ni ti awọn dokita kan ti a gbọ wipe nwọn ran apa ọmọde kan, Edie Knowles. ti ọkọ reluwe ge lapa ju silẹ, mọ ejika rẹ pada. Ko nṣe oni ni a ti ngbọ wipe awọn dokita ilu Amẹrika ti nma ran imu, oju ati ika ọwọ pọ ṣugbọn ki a so apa ti o ti ge ju mọ ara wọa sọwọn pupọ. Eyi ni akọkọ'

Nwọn ni iṣẹ a nso apa lu ti nwọn ṣe fun mọ ile-wẹ yi kiṣe iṣẹ Dokita kan, nwọn ni awọn ọjọngbọn dokita ti o mọ ọbẹ lo n nwọn jọ darijọ pọ ṣe iṣẹ na, olukuluku nmu ọgbọn tirẹ wa. Nwọn ni wakati mẹjọ gbako ni nwọn ṣe ninu iyara ti nwọn ti ara wọn mọ ki nwọn to le ran apa na pada si ipo rẹ,

Ofin nla ti awọn Dokita na fun awọn obi ọmọ na ni pe o ni lati ma wa fara han wọn ni ọsọsẹ; a gbọ wipe ọmọ na ti nlo apa na diẹd ẹ nisisiyi.

## Awolowo Pari Ejo Riro, Idajo Loku

EKO—Ẹjọ ọlọtẹ ti awọn ọlọpa mba Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, olori ẹgbẹ Afẹnifẹre (AG) ati awọn ogun enia ro wipe nwọn fẹ fi agbara gba ijọba ilẹ Nigeria pari ni ijẹta ọjọ Alamisi, o wa ku ọjọ ti Adajọ Kotu Soganran, Ọgbẹni G. S. Sowẹmimọ yio ṣe idajọ lori gbogbo ẹjọ ti nwọn ro na.

Lati bi oṣu kan ni adajọ ti da gbigbọ riro ẹjọ na duro nitori ọkan ninu awọn ọdaran na ti nwọn npe ni Samuel Onitiri ti nwọn ti nwo ninu ile awọn alaisan Ijọba ni Suru Lere fun amodi ti o wipe o nṣe on.

Nigbati nwọn bẹrẹ ẹjọ na ni owurọ ijẹta, kẹkẹ-alamodi ti nwọn fi gbe Onitiri wa si kotu, dokita kan pẹlu ọmọ iṣẹ rẹ si wa ni ẹgbẹ rẹ ti nwọn gbaa mu lẹgbẹ; bi nwọn ti pari ẹjọ ti ijẹta tan ni nwọn ti tun ru Onitiri lọ si ile awọn alaisan ni Suru-Lere, on ko ba awọn yoku pada si ọgba ẹwọn rara.

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

## Oko Akepo Tuntun Lo Si Ilu Dahomey

COTONOU—Gbogbo awọn Oyinbo asoju awọn ẹgbẹ onisowo ti nwọn nta epo mọto, awọn bi SHELL, BP, ESSO, Atlantic ati awọn bẹbẹ ni nwọn wa si ebute ọkọ oju omi tuntun ti awọn ṣẹṣẹ nkọ ni Cotonou. Eleyi ni o si jẹ ọkọ elepo kinni ti yio kọ gunlẹ si ebute tuutun na, eyi jẹki inu gbogbo awọn ara ilu Dahomey dun.

Irohin ti a gbọ lati ọdọ akọwe onirohin wa ni ilu Dahomey ni ti Ọlọla Sheu Bakre, ambasadọ (aṣoju) Ijọba ilẹ Sudan ti o gbe iwe-ẹri rẹ lọ-han Olotu Ijọba Dahomey wipe on ni Ijọba ilu na ran wa lati ma ṣe aṣoju larin ilu Dahomey pẹlu ilu Sudan, ambasadọ y ni Eko ni oa yio fi ijoko si.

Olori ilu Dahomey paapa sọrọ nibi aṣeyẹ ifiwe han yi; o ni ọrẹ ni ilu awọn pẹlu Sudan. O ni awọn mejeji ti jiya pupọ nigbati awọn wa labẹ ijọba ilu awọn ajoji o ni o si yẹ ki awọn jọ jẹ adun pọ nigbati nkan ti bẹrẹsi dara yi. Olori ilu Dahomey na tun sọ bi inu on ti dun to lati ri ambasadọ na, o ni on ti gbọ wipe awọn Ijọba ilu India paapa ti mura tan lati fi ambasadọ ti wọn ranṣẹ laipẹ yi.

## Nwon Nda Ara Ilorin Ati Kabba Duro Nibise L'oke Ọya

KADUNA—Malu ku wahala ba ọbẹ ni ọrọ ogunlọgọ awọn Yoruba ọmọ Ilọrin ati awọn ara agbegbe ilu Kabba ti nwọn gba sibi iṣẹ kan ti awọn ti nhun aṣọ ti nwọn bẹrẹsi si da wọn duro ni ẹnu ṣẹ na lati ọsẹ ti o kọja yi.

Onirohin Eleti-Ọfẹ ti o wa l'Oke-Ọya tẹ waya si wa pe laipẹ yi ni awọn alamojuto ti o wa lẹnu iṣẹ aṣọ hunhun ti awọn ẹgbẹ kan ti nwọn npe oruko wọn ni Northern Nigerian Development Corporation ẹgbẹjọda Ipinlẹ Ariwa ṣe ikede wipe awọn fẹ da enia diẹ duro nibi iṣẹ na tobẹ.

Mo gbọ wipe nigbati nwọn fẹ lati ma da duro ọdọ awọn Yoruba ara Ilọrin ti uwọn wa lenu iṣẹ lọgba na pẹlu awọn ara agbegbe Kabba ni nwọn bẹrẹsi daduro lai boju wo ẹhin rara.

(Wo yoku loju ewe keji)

## Iyaafin Mada Palemo Ominira Dahomey

IYA-AFIN MADA t'ṣe iya ẹgbẹ gbogbo awọn obinrin ilu Ajaṣẹ ti ko gbogbo awọn obinrin ilu na jọ lati ṣe ipalẹmọ ajọdun ọjọ ti nwọn gba ominira ni Dahomey ti nwọn yio ṣe ninu oṣu August ti mbọ yi, Onirohin wa ni a wọn ara ilu Dahomey lati nkan ti o bẹrẹ lati Cotouou, Porto-Novu titi ti o fi de gbogbo ilu Oke Dahomey ni nwọn ti nmura lati ṣe bẹbẹ ajọdun kẹta ominira na.

Mo gbọ wipe alamojuto Ijọba ilu Dahomey Ọgbẹni Hubert Maga paapa pẹlu awọn minisita rẹ ti nṣe ipalẹmọ ajọdun ominira ilu na ni ẹkunrẹrẹ. Awọn enia mẹta pataki ni Ijọba Dahomey ran lọ si ilu Ro-

(Wo yoku loju ewe keji)

# Awon Egbe Onina Eletiriki Pe Awa-moto Kan Lejo

IKEJA — Awọn Oyinbo onina elẹtiriki pe baba oni-moto ayọkẹlẹ kan Ọgbẹni C.N Eneli akọwe agba ni-bi ile iṣẹ minisita alamojuto nkan Aje ati owo, ati dẹrẹba rẹ, Charles Offodile ti o nwa mọto na lọjọ ti nwọn wa moto wọn kọlu opo ina ẹlẹtiriki ni Ikeja.

Ninu iwe ipẹjọ na ti nwọn ha fun awọn mejeji ni ijẹta, awọn ẹgbẹjọda onina ẹlẹtiriki yi (E.C.N) ni ki Adajọ Koto ganran ba awọn gba ẹgbẹtala o le adọta pọnun (2,950:15s) lọwọ awọn mọjeji fun opo ina wọn ti nwọn wo moto ayọkẹlẹ wọn lu ninu oṣu keji (February) ọdun yi ti nwọn si ba a jẹ.

Nwọn ni alẹ ọjọ na gbogbo na awọn onibara won ni o ku bamubamu lowa agbẹjọre awọn ẹgbẹjọda onina manamana, Ọgbẹni S.A Shitta-Bey tun ṣaleye ninu iwe-ipẹjọ naa wipe lojn ọna ti o lọ si ebute ọkọ ofurufu ni Ikẹja ni nwọn ti wa moto na lu opo ina awọn na.

Nwọn ui awọn si kọwe bere owo nkan ti awọn onimoto na bajẹ lọwọ wọn titi nwọn ko san an rara. Ninu oṣu ti mbọ yi ni nwọn yo lọ ro ẹjọ na ui-waju Adajọ Kotu ganran.

Ọgbẹui Charles Madarikau ni Ikẹja

# Awon Egbe Oselu Ara Ilorin Ati Kabba Gba Iwe Idaduro

(O bẹrẹ loju ewe kinni)

Gẹgẹbi irohin ti a gbọ, nwọn ni o to ẹdẹgbẹta (500) enia ti nwọn da duro ninu awọn oṣiṣẹ ninu ọgba awọn ahunṣọ, Kaduna Textiles yi. Eyi ti o wa jẹ iyanu fun wa ninu ọrọ na ni ti iwe-idaduro na ti o jẹ pe ọpọlọpọ awọn Yoruba ti o ba ti ti agbegbe Ilọrin wa ni nwọn ha ni awọn iwe na pẹlu ọmọ ilu Kabba.

Ọkan ninu awọn oṣiṣẹ na ti orukọ rẹ njẹ Abudu Karimu Olorukọba ni ko ye awọn si nkan ti awọn gbe ninu igba Oyinbo ọga ibi iṣẹ na ti orukọ rẹ njẹ J D Gomwalk. O dabi enipe nwọn yan si awọn nitoripe awọn nkan ni o doju kọ.

Irohin ti kan wa wipe awọn ọmọ Ilorin ati awọn Kabba tio oṣiṣẹ ti gbara jọ, nwọn si ṣe ipade kan ni ijẹrin, nwọn si ṣe ipinnu lati kọ iwe-ẹbẹ si alaga ibiṣẹ ẹgbẹjọda na, Alhaji Muhamadu Ladan ati akọwe ẹgbẹ oṣelu ti nwọn npe ni ẸGBẸ OLOMI (N. P. C.), Alhaji Ahman Galadima Pategi, pe ki nwọn gba awọn lọwọ Oyinbo ọga iṣẹ yi.

Ọpọlọpọ awọn ni awọn wa ninu ẹgbẹ yi, ko si yẹ ki nwọn ma wo awọn bayi. O dabi enipe awọn olori ẹgbẹ awọn na ko fẹ nani awọn rara.

Oyinbo ọga iṣẹ Gomwalk ti awọn oṣiṣẹ yi nlọgun kiri yi ni iro ni nwọn npa mọ on; O ni ọrọ na ko lọ bi ti nwọn nsọ kiri. O ni ọrọ oṣelu ni nwọn fẹ ko wọ ibi iṣẹ on. O ni on ko fẹ mọ bi Hausa ni ẹnikan, bi Fulani ni awọn miran, iṣẹ ti nwọn fun on tọju ni on koju mọ.

Ọgbẹni Gomwalk ni awọn Yoruba ti nwọn nbinu tenu bọlẹ kiri ni nwọn pọ jamburata ninu ọgba iṣẹ awọn na; ko si orilẹ kan ti o pọ ju wọn lọ bi a ba ka gbogbo awọn lebira ati akọwe awọn nibi iṣẹ aṣọhunhun yi.

# Oro Behin Yo!

# Nwon Ro Tshombe Loye Olotu Ijoba

LOEPOLDVILLE—Ọrọ lẹhin yọ ni ilu Kongo, awọn ọmọ ile igbimọ aṣofin ti o pejọ sile igbimọ ni ijẹta ni ilu ti nwọn npe ni Leopoldville fi ọwọ si ofin pajawiri kan lati da ipinlẹ tuntun kan sile ti nwọn s npe ni Ipinlẹ Ila Orun ilu Katanga, ofin na ni nwọn fi ro Baale Moise Tshombe tiṣẹ Olotu Ijọba isalẹ Katanga loye Olotu na.

Gẹgẹbi irohin ti a gbọ ati Congo wa, nigbati awọn ikọ ile igbimọ na fi fọwọ si ofin tuntun yi Ọgbẹni Tshombe alara paapa ko si nile, o lọ si ilu Faranse ti nwọn npe ni Paris nitoripe ara rẹ o da, o si fẹ ri awọn dokita Oyinbo Faranse fun isan na.

A gbọ wipe gbara ti Ọgbẹni Thombe ti gunlẹ si papa ọkọ ofurufu ni awọn onibode ebute ọkọ furufu ti sọ fun un wipe awọn ko ni jẹ ki o wọle nitori iwe aṣẹ iwọlu (passport) ko rẹ tọna rara.

Nwọn sọ ọrọ na titi, atẹhinwa atẹhinbọ, awọn onilu na wa yọnda fun Ọgbẹ ni Tshombe lati lọ si ibugbe ti n ọn npe ni Chinique De Passy lati wo arun ara rẹ nibẹ.

Awọn onirohin kan ni awọn ko le sọ boya Ọgbẹni Tshorabe yio tun pada silu Congo ilu rẹ mọ, nwọn ni o le fi iti u salọ si ilu miran ti o ba wo ara rẹ tan.

# Aiyelujara: Lemomu Medina Wole Yi Wa

KANO — Aiyelujara ni asiko ti a wa lode isisiyi, Lemọmu ilu Mẹdina ni agbegbe Mẹka ti gua silẹ yi ni irọlẹ ana pẹlu awọn ọmọlẹhin rẹ awọn, mẹta kan. Gbogbo awọn alufa onilawani nlanla ni nwọn wa si idi ọkọ ofurufu lati wa pade Lemọmu na.

Ọpọlọpọ awọn ọmọkeu pẹlu awọn alufa wọn ni nwọn na to si idi ọkọ ati wa mọ Lemọmu ilu Mẹdina na. Irohin ti a gbọ npa wiwa ti o wa sile wa yi ni nipa ti Mọsalaṣi tuun ti nwọn npe ni MỌṢALAṢI Bello ti nwọn ni ki o wa ba wọn ṣe aṣeyẹ ṣiṣi rẹ ni Kaduna.

Ni ọjọ Jimọ ti ọjọ mẹje loni ni nwọn yio ṣe adura lati ṣi ile isin Mọṣalaṣi tuntun na. Onirohin wa ni on gbọ wipe orukọ Ọba ilu Ṣokoto ni nwọn fi sọ Mọsalaṣi tuntun na, owo nla ni nwọn si fi kọọ. Mọsalasi keji wa ni Sokoto mejeji ni yio ṣi.

Lẹhin Lemọmu ilu Mẹdina yi ba ti ṣe adura iṣi Mọṣalaṣi na tan yio fi ẹsẹ kan de awọn ilu bi Zaria, Katsina ati Ṣokoto. Gbogbo awọn alufa ilẹ Hausa ati awọn ọba ni nwọn ti nmura lati gba a ni alejo; ọjọ mẹwa gbako ni yio ṣe ni ilu awọn Hausa ti o wa na.

## ger Paapa Ti De S'Eko

k Tiger, a-bi-ese-ku-bi-alara 'paapa ti ba oko irufu gunte si ilu Eko ni ijarun lati lu Amerika, gbon ko mu Oyinbo kan io ma ba fi ese danra lowo. O ni inawo lati iru enia be wa si Nige- ko nse nkan kekere a.

Awon Oyinbo meta ni on ba a de; Ogb ni bby Diamond, oga re ilu Oyinbo je okan ninu n, wọn yoku ni Ogbeni anny Shap, asoju Tiger a pelu Og eni Jimmy gust, eniti o nko o lese .

Nwon ni Ogbeni August nko awon enia lese lati odun mejilelogun sehin, unrin yi ni o nko Hogan ssey nigbati o nja ese ilu Oyinbo

'o yoku loju ewe kejo

# Enyin Onimoto E Fi Eyi Kogbon




Ti o ba je dereba ti o nsa moto, O ye ki o ma se akiyesi gbogbo nkan ami ti nwon kan mo eb -ona ti o ngba. Mase fi moto re sare lati koro bo si gbangba oju ona lojiji; bi o ba fe de ileto abule tabi ibiti nwon ko ilewe si ki o de are ti o ba nsa bo. Emi enia ko se ra loja, nitorina mase fi moto re sare isakusa ni oju titi.

O BA NWÁ 'UNRA RẸ"

se opolopo aworan i wungi lati ma wò , eyiti iwọ papa ti oran yi je itan nipa kan ti baba rẹ ran wà ọrọ̀ funra rẹ. lo pade enia mẹta: on ni mọto nlá ti a



keji je arugbo, ẹketa l'ọrọ̀. Awọn wọnyi o owo wọn pamọ , wọn si ti lowo dá imọran fun wipe Barclays Bank lati mọ sibẹ. a to wà ninu mọto



alaye bi owo rẹ yio ninu banki na yio a owo na mọ sinu le to tobi. Ki o si mọ gba ti o ba nfẹ owo ibẹ. Iwọ na gbọdọ pamọ bẹ gẹgẹ.

BARCLAYS BANK D.C.O.

## Awon Iwe Asiko:

# Aggrey Omo Ilu Afrika (3)

### Lati Inu Iwe ALUFA ATILADE

Eleyi ni Apa Keta itan igbesi-aiye Dokita J K Aggrey, omo ilu Aganyin ti o se bebe ninu eko giga awon enia dudu Iwo Orun Afrika. A da iwe yi lati inu iwe Alufa (Rev) E A. Atilade ti a npe ni AKO-KA YORUBA (Apa Karun) ti e le ri ra ni No. 6, Ashabi Street. (Ogunmokun Road), Mushin, tab ti e ba fe ko iwe bere, e kowe si apoti iwe P. O. Box 263, Ebute-Metta. E ma ka itan na niso.

Ni odun 1924, Aggrey pada wa ile lati je ipe na. Bayi ni Aggrey di okan ninu awon oluko agba ti o wa ni ile eko giga ni Achimota, lebi Accra ni Gana Ise ti Achimota College yi nsese nfi ese mule dada ni Aggrey rin irin ajo pada lo si Amerika. Lori irin ajo yi, ni aisan gbe kolu, o si ku ni New York ni Amerika ni odun 1927. Gbogbo enia dudu ati enia funfun ni Afrika English ati Amerika lo daro iku Aggrey.

Eko giga nikan ki o mu ki okiki Aggrey kan bi eni nla ikese iwa rere re pelu. Aggrey ko ni pe awa enia dudu ni lati so owo po lati ran ara wa lowo. Ki ise pe kiki awon ara Gana ikan ni Aggrey feran tikose gbogbo enia Ile Afrika, ibi yowu ti nwon le ti wa, eya yowu ti nwon le je, ede yowu ti nwon le ma so. Nitori eyini a se npe okunrin olokiki yi ni Aggrey ti Afrika.

A tun le pe eni yi ni woli repo ti awon orile ede; nitori pe o tun nwasu je awon enia dudu ati enia funfun ni lati le jo jumo fi-owo so-owo fun fun ilosiwaju ati anfani ara won. Lori eko yi ni o gbe ma nlo apere ti d ru O so pe ki a to le gbo orin ti o kun ni ori duru, a ni lati te awon ike dudu ati awon ike funfun po. Bi a ba te kiki ike dudu nikan tabi kiki ike funfun nikan, a ko le gbo ohun ti o kun lori duru. Enia dudu ati enia funfun ni lati jo jumo pa owo po fun irepo, ilosiwaju ati alafia.

A! Iku doro! Iku doro!
Iku p'oba o si tun pa mekunnu;
Iku p'elowo, iku p'alagbe.
A! Iku doro! Iku doro!
Iku pa'eleko ila, ara ile wura;
Omo a fopon owo jeun.
A! Iku doro! Iku doro!
Iku p'Aggrey Afrika t'awa;
Omo igbo elerin, igbe ope.

# Eka Iwe Irohin Ayiluka

## Ti O kun Fun Oro Ologbon at Ilakaye ni Oju ewe karun.

# ELETI—OFE

A NJU WỌN KO ṢE WI LẸJỌ

EDITORIL OFFICE & WORKS 28, Kosọkọ Street, Lagos. CABLE & TELEGRAMS "ELETI-ỌFẸ" LAGOS

P. O. Box 467 Phone 23370

VOL XIV. NO. 875 SATURDY JUNE 29 — JULY 5 1963


## Oro Olotu:

# Iku Ti Wo'le Adun

### Maggie

Nwọn ni bi iku ba npa ojugba ẹni ominu a ma da kọ ni : Ọfọ meji n'la kan ṣẹ nilu Eko ninu ọsẹ ti o pari loni ti nwọn mi ọpọlọpọ awọn ọdọmọkunrin arin wa lọkan pupọ nitoripe ọdọmọkurin ni a le pe awọn mejeji ti o jalaisi na.

Ekinni ni ti LỌYA MAGNUS ARCHIBALD ỌLAWUNMI WILLIAMS ti o jalaisi ninu ile iwosan ti nwọn npe ni Lagos University Teaching Hospital ni Suru Lere. Oṣu meji gbako ni aisan ti o pa na fi ṣe e gba. Ẹni ọdun mẹrindinlọgọta ni ologbe na ki o to filẹ bo ara bi aṣọ.

Maggie jẹ ọkan ninu awọn ọmọ ilẹ yi ti o ja rabarabu ki ominira to te wa lọwọ. Bi o ti nṣe wahala lati kọ iwe sinu iwe irohin igbani lati tọka alebu awọn Oyinbo ti o nṣe alamojuto Ijọba wa fun wọn, bẹni o tun nfi iṣẹ lọya rẹ ṣe anu fun awọn ti ọlọpa ba mu ni ẹna ti ko tọ.

Bi o ti ni anu to ọpọlọpọ ọmọ ọlọmọ ni o ran lọ si ilewe lọfẹ. Bi o ti nṣe anu fun alejo ni o nṣe fun awọn ọrẹ. Ologbe Maggie ko fẹ mọ ilu ti o ti wa ati wipe tani o bi ọ. ni iwọn igba ti o ba ti rii wipe awọ ara rẹ dudu o ti ṣe tan lati ran ọ lọwọ.

Awọn agbalagba ni anu ki pa enia ṣugbọn o ma nko wahala ba ni. Bi awa oniwe irohin ti ni Ologbe Lọya Maggie Williams ti ṣe enia oninurere to yi ko ṣe alai mọ ni awọn ti o mbinu rẹ. Nkankan ni a mọ daju, iyẹn ni wipe oja ni ile aiye ti a wa yi, olukuluku wa si ni lati jere iṣẹ ti a ba ṣe, yala o jẹ rere ni tabi buruku ni.

A tun mọ nkankan daju eleyi ni wipe bi o tilẹ jẹ wipe Lọya Magnus Williams jalaisi, iwa-rere ti o hu sinu aiye si wa lẹhin.

### Mattar

Ẹnikeji ni ọdọmọkunrin Kora onişowo kan, Ọgbẹni Joseph Khodor Mattar ti o nade agbako jamba iku moto lori kereni Eko ni owurọ kutukutu ọjọ ọsẹ ti o koja lọ yi.

Boya ẹnyin ọkawe wa le sọ wipe kinni o kan wa pelu ọrọ awọn Kora ajoji wa wọnyi. Idahun wa si iru ibere bayi ni pe, ọpọlọpọ wọn ni nwọn ti fẹ sọ ara wọn di ọmọ onile, ti nwọn si ti fi ara ro wa fun ọpọlọpọ ọdun, iru wọn ni Ologbe Joseph Mattar yi. Ẹni ọdun mẹtalelogoji niṣe, ọmọ kekere ni awọn obi rẹ ti gbee wa s'Eko.

Ni ilu Eko yi na ni o gbe ti lọ ile ẹkọ, nibẹ na ni o si ti ṣ'owo ti o si ti jere. O ti di Yoruba; o si jẹ ẹniti o lawọ pupọ.

Nkan ti o dun wa ninu iku ti o mu u lọ ni ojiji ni pe akoko ti a ba bẹrẹsi gbadun iṣẹ rere rẹ ni iku gbee lọ mọ wa lọwọ.

A! Iku doro! Iku doro!
Iku p'ọba, o si tun pa mẹkunnu;
Inu p'olowo, iku p'alagbe,
A! Iku doro!

# Iwe Si Olotu

## 'Ogun Kekere' Ni Eyi Tabi Kinni?

CALABAR—Ọgbẹni oṣelu kan ti orukọ rẹ njẹ J A Brown ni irọ ni irohin kan ti a gbọ lati ilu Kalaba (Calabar) wipe atẹgun nla kan kolu ọkọ awọn onişowo kan ti nwọn mbọ lati Fernando Po nigbati nwọn de Oron, o si ri ọkọ mẹrin ninu ọkọ ti nwọn fi nko ẹru ọja wọn bọ wa sile ati pe enia marunlelọgọta ni nwọn ri ti nwọn ku patapata si odo na.

Ọgbẹni Brown ni ti Ijọba Apapọ ṣe l'Eko ko ba ṣe paramu ki nwọn sọ otitọ nkan ti o wa ninu ọrọ na jade fun gbogbo araiye gbọ on yio tu gbogbo aṣiri wọn jade.

Oṣelu Brown ni gbogbo irohin nkan ti o ṣẹlẹ lọjọ na nibiti awọn onibode ti gbe "Ogun Kekere" kan ko awọn onişowo yi wa lọwọ on; Ọgbẹni na ni igba (200) enia ni awọn onibode na yinbọn pa lati inu ọkọ ofurufu ti nwọn ngbe kiri. O ni on ko fẹ ki nwọn fi nkankan bo fun awọn ara ilu nipa ọrọ na rara.

O ni lai ṣiro awọn igba enia ti awọn onibode na yinbọn pa bamubamu adọjọ enia ni ọta ibọn wọn tun ṣe leṣe, ti nwọn ru wọn lọ si ile awọn alaisan ni Oron Methodist Hospital ti nwọn ntọju wọn lọwọ nisisiyi.

Onirohin wa ni on gbọ wipe Ọgbẹni Brown ti tẹ waya si Ọlọla Tafawa Balewa ni Bauchi wipe ki o tete pada si Eko ki o yan awọn ti yio ṣe iwade ọrọ na ni kiakia.

Mo gbọ wipe ẹru awọn onişowo na ti nwọn ṣegbe sinu odo ti nwọn ri si na fẹrẹ to ọkẹ marun pọnun. Ọgbẹni Brown ni awọn ti gbọ ki awọn aṣoju Ijọba gbogun ti awọn ara wa bayi ti pe, eleyi dabi ti awọn awedu Enugu ti nwọn yinbọ pa ninu ọdun 1949.

## Nwon Ti Da Won Si Tubu

S- Africa—O fẹrẹ jẹ gbogbo awọn ara ilu ti nwọn npe ni South Africa (isalẹ Afrika) ni awọn Alamojuto Ijọba ibẹ fẹ fi pamọ si ile ẹwọn tan. Gẹgẹbi ikede ti awọn alamojuto Ijọba ilu na paapa tẹ sode, nwọn ni o le ni ọkẹ meta o lẹ ẹdẹgbaria enia ti nwọn ti de mọlẹ ni ọgba ẹwọn lori ọrọ ilu.

Nwọn ni awọn bi ẹdẹgbefa enia (11,000) si wa lọtọ ti nwọn ko ti ṣe idajọ awọn yẹn rara. Ajẹlẹ ile ẹwọn ni o le ni ẹgbẹdọgbọn enia ti awọn ti mọle nitoripe awọn fura si wọn wipe nwọn lé ṣe jamba fun ijọba.

Nwọn ni awọn ẹgbẹ kan wa ti orukọ wọn njẹ POQO, nwọn ni o le ni ẹgbẹrindinlogun enia ti awọn sọ sinu tubu ninu awọn ọmọ ẹgbẹ na.

Ọgbẹni Balthazar Voster, tiṣe minisita alamojuto idajọ ni on ri wipe awọn ọlọpa ilu na ti ṣe bẹbẹ nisisiyi ti nwọn ti ko awọn ọmọ ẹgbẹ POQO na lọ fi pamọ si ọgba ẹwọn.

Gbogbo awọn ọmọwe enia dudu ilu South Africa na ni awọn ti lọ fi si ọgba ẹwọn nitori ki nwọn le ma mu ẹnu kan ọrọ ominira ilu awọn mọ rara.

Ayiluka Ni.

# Omo Olowo Nfe Omo Oloro

Irohin kan ti mo gbo nipa iyawo alarinrin kan ti nwon fe se ni ilu Oyinbo loni n ti omo Alhaji Lasisi Ojikutu ti oruko re nje Sadatu Adebimpe ti nwon fe fa fun Ogbeni Suraju Bello, omo Ologbe Alhaji Olatunji Bello ti ita Ajisomo l'Eko. Mo gbo wipe bi nwon ti nso yigi iyawo na lowo ni ilu London ni baba iyawo paapa si nse aseye iyawo tire pelu ase nla fun ore, awon enia jankan jankan ni ilu Eko.

Gegebi iwe-ipenia (invitation) ti baba iyawo na ha fun awon ti o pe, Olola Dokita Moses Adekoye Majekodunmi, minsita alamojuto eto ilera ni yio se alaga ni ibi ase na, Oloye Wahabi Balogun, Asiwaju ilu Eko ni yio se BABA-ETO aseye ti iyawo na.

Mo gbo wipe eleru a sun igi nibe nitoripe awon ebi Alhaji Ojikutu, awon bi Balogun gbogbo ara ilu Eko, Oloye (Alhaji) Abudu Yekinnni Ojikutu paapa ti mura tan lati fi owo dabira loni nibi iyawo na. Emi AYILUKA a fese kan de ibe. O dun mi ti baba oko iyawo na ti jade laiye, gbogbo awon Egba lati AGO IKA, AGO-OWU ati awon omoge GBAGURA ni Abeokuta ni nwon ko ba wa jo ilu-asiko fun won ni ita Ajisomo l'Eko nitoripe gbogbo awon obi oko iyawo ni emi Ayiluka mo bi eniti o mo owo. Ehin iyawo na ko ni m'eni.

## Maggie Orun Re

Nwon ni ibiti elekun gbe nsokun ni alayo nyo; eyi ti



OLOYE A Y. OJIKUTU
Olori ebi awon Ojikutu niyi.

mo so nipa ti awon oniyawo yi to, o wa ku ti ore mi Loya Magnus Williams ti o jalaisi ti nwon sin ni ojo Wednesday ijerin l'Eko. Bi a ba nsoro nipa awon oselu ile Nigeria ti nwon so gbogbo nkan dero lode oni fun awon ti o wa nla obe, ore mi Maggie ko se fi owo ro sehin rara. O nawo, o si tun na ara lori oro ominira ile yi ki awon Oyinbo to gbe gbogbo re le wa lowo pe ki awa na ma ba a yi, INU RE LA WA YEN.

Bi o ti nfiwe re da nkan ti ko ni tan sile fun awon Oyinbo oga oselu wa nighana ni o tun nfi isegi ejo ro re se ore fun ogu logo enia. Mo niran oruko kan ti a soo nighana bayi „BETWEEN OURSELVES" n to ipe oro yi ni o fi se o i iwe ti nma ko nigbakugba sinu iwe irohin.

## Ejo Kembi

Bi a ba nsoro Loya MagnusWilliams a ko gbodo gbagbe gbogbo awon ejo nla ti o se ni Kotu ganran ni ita Tinubu bi ti ejo apania ti awon olopa bu baba onighanjo ara ilu mi, Ogbeni Kembi se lori oku akowe Reluwe kan, Oshinaike ti nwon ni nwon sa pa ni Little Road ni Yaba.

(Wo yoku loju ewe kejo)

Comfortable and safe



A roomy 5-6 seater, space for lots of luggage, luxurious appointment, excellent finish, a very high standard of safety; these and many other welcome features you find in both of the 190 models and besides the 190 Diesel offers quite exceptional economy. Let us demonstrate by a trial run, free of any obligation, what excellent value these cars represent.

MERCEDES-BENZ

LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS: (E.B.) IBADAN: KANO KADUNA: JOS: PORT-HARCOURT: ABA.

Sub—Distributors:

ARMELS TRANSPORT LTD.

BENIN CITY: ONITSHA: ABA.

# Oselu Aganyin Ti o Sa Kuro Nilu Ku

IBADAN–Ọkunrin Aganyin kan to sa kuro ni ilu rẹ nigbati awọn alasẹ ilu Ghana fẹ fi ofin mu lọ si ajaile fun ọdun gbọrọ ni a gbọ irohin wipe o alaisi ni ile awọn a'aisan ni ijẹsan; oruko Ogbeni ... ni G. Ashie-Nkoi, ẹni ọdun mẹrinleladọrin nisẹ.

Okunrin na jẹ ọkan ninu awọn oṣelu pataki Aganyin ti nwọn da ẹgbẹ atako kan ti orukọ rẹ njẹ United Party silẹ. O to wọn nkan bi ọdun kẹrin sisiy ti nwọn fi ofin gbe ... gbẹni na ti mọlẹ.

Ọdun meji ni o ṣe ninu ... amọ na ki dokita kan ti sọ wipe ki nwọn sọ ọ silẹ ... rẹ ti ko a ... hin ... awọn tun fẹ fi ofin mu u ki o to sa kuro ... u lọ si ilu ti nwọn npe ... Lome. Ko rẹ ti o sa kuro ni Lome. ... a fi ara pa... ni Nigeria.

N... Ibadan ni ọgbẹni na ... be, ... na ni o wa ni ... n ti o sọ wipe ara on ko da, ki nwọn to mu u lọ si ile alaisan ni Orita-Mẹrin Ibẹ ni o jalaisi si.

Agbẹ onikoko (cocoa) ni Ọgbẹni na, o si jẹ ọkan ninu awọn ti nwọn sa agbara titi lati le gbatominira ilu Aganyi lọwọ awọn Oyinbo. On na kọ fi igba kan wọn ẹgbẹ oṣelu ti Dokita Nkrumah da silẹ, nigbati ina ko wọ mọ ni o kuro ninu ẹgbẹ na.

---

## Olopa Mu Janduku Oyinbo Onibon

JACKSON—Ọwọ awọn ọlọpa ilu Amẹrika ti tẹ Oyinbo janduku kan ti o yinbọn pa Ọgbẹni Medgar Evers, alawọdudu ti o nja fun awọn enia dudu ara rẹ. Byron De La Beckwith ni oruko ti nwọn npe baba onibọn na, nwọn ni ewe-taba ni o nta ni ilu ti nwọn npe ni Greenwood ni ilu Amẹrika.

Lọjọ ti nwọn ra ẹdaran na mu, awọn ọlọpa nu mẹta ni nwọn tẹ e lọ si ile iṣẹ awọn ọlọpa lati lọ gba ọrọ lẹnu rẹ. Nwọn ni o fẹran a nko ibọn kiri, o si ma nta awọn ibọn ti o ba ra ni alọku kiri.

Ẹsun wipe o pa Ọgbẹni Evers lọjọ kejila oṣu yi ni awọn ọlọpa fi sun un. Nwọn ni o yinbọn lu ni ẹhin ọrun bi o ti bọ silẹ ninu mọto ayọkẹlẹ ti o lọ si ibi ipade kan ti awọn enia dudu ṣe lori awọn Oyinbo ti nṣe inunibini si wọn nṣe nunibini si wọn ni.

## Ija "Tiger" Pelu Fullmer Di Igbamiran Ni Ibadan

NEW YORK — Ija ẹṣẹ ti Ọgbẹni Dick Tiger ati Gene Fullmer fẹ ja ni ilu Ibadan ninu oṣu ti mbọ yi, ko ni bọ si mọ nitori jamba kekere kan ti o ṣe Ọgbẹni Fullumer ti nwọn jọ fẹ ja.

Irohin ti a gbọ lati ilu Amẹrika ni pe Fullumer ti ẹṣẹ rọ nibiti o gbe ti nmura fun ija na ni Agọ kan ti nwọn npe ni West Jordan.

Ọga Fullmer ti orukọ rẹ njẹ Mary Jenson ni o tẹ waya sọ fun ọga Tiger ni ilu Oyinbo. Iyanu pupọ si ọrọ na jẹ fun gbogbo awọn ti o gbọ ọ, nitoripe ogunlọgọ awọn enia lo ti lọ mura, ti nwọn ti sanwo silẹ fun ere ẹṣẹ na.

---



Iwọ ha nwá asiki funra rẹ bi?
Ki yio pẹ lọ titi fun ọ bi o ba nfi owo pamọ
latigba dẽgba nile ipamọ owo ti Barclays

Owo rẹ mbẹ labẹ abo lọwọ Barclays. Ki yio sọnu wipe bi o ti npẹ nibẹ si bẹni yio ma lési. Lọ bẹrẹ nibiṣẹ Barclays tombẹ nitosi ọdọ rẹ nipa fifi owo pamọ ki o si bẹrẹ lati ṣe bẹ ni kiakia.

Thanks To Great Britain:

# More Food For Hungry World

LONDON— The British Government has pledged a single contribution of five million dollars to the world food progamme ot the Food and Agriculture Organisation, the Lord Privy Seal, Mr Edward Health, informed the House of Commons yesterday.

He added that half would be in cash for shipping services and half in commodities.

The World Foood Congress in Washington has paid tribute to Britain for making by far the largest contribution to the United Nations sponsored FREEDOM-FROM--HUNGER CAMPAIGN. Fifty countries took part in the Campaign and an Indian delegate has suggested that the British response to the special week was due to the strong spirit of voluntary service prevailing in Britain.

## Hovercraft Services Start In England

LONDON—The first 42-passenger Hovercraft service between England and Wales across the 10-mile Bristol Channel is due to start soon.

A Westland SRN 2 will operate commercially between Weston-Super-Mare, a holiday resort in Somerset, and Penarth on the Welsh coastline.

By steamer the journey takes 40 minutes. The Hovercraft will cut the time to ten minutes, travelling three or four feet above the water at a top speed of 70 knots.

## New British Medicine For The Blind

LONDON—A British-developed vaccine against blindiness has proved so successful in Gambia that full-scale experiments are to be made with it in Iran and Iraq in Middle East.

This has just been announced in London by Sir Stewart Duke-Elder, the British eye surgeon who is Hospitaller of the Order of Saint John of Jerusalem.

The Order shares with the Medical Research Council the costs of research in London and Gambia, which is now concentrated on the elaboration of a vaccine against trachoma in children-the biggest single cause of blindiness in the world.

In some areas up to ninety-five or even one hundred per cent of children are infected with the virus before age of ten.

## Britain Rejects Russian Plan For Nuclear Free Zone (By Special Correspondent)

LONDON—The British Government yesterday rejected as "transparently propagandist" a Soviet proposal from a nuclear free zone in the Mediterranean.

In a Note handed over in Moscow the British Government pointed out that the present situation with arms of all sorts stationed throughout the world was "a situation of the Soviet Union's own choosing."

The Soviet proposal was made in a Note of May 20-a move deliberately designed as a Communist propaganda shot in advance of last month's meeting of the NATO Ministerial Council in Ottawa.

The United States Goverment last Monday rejected the Soviet proposal in similar terms to the British Note.



## First Woman To Study Naval Architecture In Britain

Nowadays a passion for sailing boat is not rare among girls in Britain. But the only one so far to have a passion for designing them as well is 19-year old Miss Anne Chambers, who has just finished her first year of a three year course in naval architecture at Sunderland Techinical College, northern England.

Born in Devon, that famous county of seamen, Anne is taking a "sandwich" course for her college diploma. After spending six months of each year at college, she returns to her job for another six months in the drawing office of the Morgan Giles shipyard in Teignmouth, where she helps in the production of ocean yachts and cruisers.

## Isin Ijade Isinku Iya Alufa Atilade DuN

AWE (lẹti Oyọ)—Ni ijeje ọjọ ọsẹ (Sunday) ni awọn ọmọ ọmọ, ọmọ ati awọn ọmọlẹbi Ologbe Iyaafin Dorcas Ẹyeronkẹ Atilade ti o jalaisi laipẹ yi ninu ile ọmọ rẹ ni-ọwọ Alufa ((Rev) E A. Atilade ni Mushin ti nwọn si gbe lọ sin ni ilu rẹ ni Awe, Ọyọ, ṣe isin-ijade oku rẹ ninu ile isin awọn Ijọ ti nwọn npe ni Christ Baptist ni Awe.

Eni-ọwọ Alufa D.A. Ọlaopa ni o ṣe Olotu isin ijade oku na, gbogbo ẹsẹ awọn alufa Ijọ Ṣọsi onitẹbomi (Baptist) lo pe sibẹ ati awọn ojiṣẹ Ọlọrun ti Gospel Baptist Church ti Alufa Atilade ọmọloku da silẹ jake jado ilẹ Nigeria. Ninu awọn Alufa ti o wa nibi isiuku na ni Eni-ọwọ Alofa J. A. Lawọyin, Alufa S. A. Onifade ati awọn bẹẹbẹ.

### Isin T'Eko

Bi awọn alufa ojiṣẹ Ọlọrun ti pọ to nibẹ, bẹna ni awọn enia pataki pataki lati Ibadan Eko ati Abẹokuta. Ọmọ ọmọ Ọloku, Ọiya Paul Atilade ko gbogbo awọn lọya agbẹ rẹ wa lati Eko ati Ibadan, nwọn si ṣe bẹbẹ nibi isin ijade oku na.

Agbọ wipe ni ọla ọjọ ọsẹ (Sunday ni awọn ọmọloku yio ṣe isin-iranti (Memorial Service) ni Ṣọsi Gospel Baptist ni 70a, Apongbon Street (Itọlọ) l'Eko ni agogo mewa owurọ fun ologbe iya wọn na. A ki yio, ẹ ku asẹhinde, ẹ si ku inawo.

## Ayiluka Ni: Maggie Lo

(o bẹrẹ loju ewe keriu)

Ẹjọ na ha ti a gba iyawo kan ti nwọn npe ni IBIDUN lọwọ KẸMBI ni Oko-Baba lEbute-Metta lọ. 'Nwọn ni Kẹmbi ni, Maggie ni Kẹmbi kọ; Maggie sọ, sọ, niwaju Adajọ. Kẹmbi wa jare ẹjọ; Maggie o sọ, o yọ Kẹnbi ninu ẹjọ Ọṣinaike.'

Ọjọ nla pẹlu orin nla ni ọrọ ti ẹmi Ayiluka niran yi, ilu Eko mi titi nigbana; iṣẹ lọya si jẹ nkan ti o tun niyi n gbati mo nsọ itan rẹ fun yin yi.

K ọrẹ mi Maggie to jalaisi yi ninu ile faaji kan ti a npe ni WAKA ni Itẹoku igboro ni mo ri gbẹhin. Mo gbọ wipe awọn ẹmẹwa wa ti o nwa si WAKA na ṣe bebe ni ibi aisun oku rẹ. Maggie, ọrun rẹ!

## Awolowo Pari Ejo Riro, Idajo Loku

(O bẹrẹ loju ewe kinni)

lẹhin ti awọn agbẹjọro ọmọ ti sọ fun adajọ wipe awọn pari ẹjọ awọn, idajọ ni o ku ti awọn nreti ni adajọ paapa wa sọ fun wọn wipe a gba on ni asiko diẹ ki on to le ṣe idajọ na. Ọ. Ọvẹ. Awolọwọ ni ki adajọ ṣe gbogbo iya ti awọn ẹṣẹ ni ọgba ẹwọn ki o ṣe awọn ṣe idajọ na ni ... ki awọn le mọ ibiti awọn nlọ.

Adajọ Ṣọwẹmimọ ni ko wa ... on lati jeki ọjọ idajọ na tale rara ṣugbọn on fẹ ki nwọn mọ wipe iṣẹ kekere kọ ni ẹjọ ti nwọn fi oṣu mẹjọ ro, nitori na a to ọsẹ mẹta gbako ki on to le kọ gbogbo rẹ iwe idajọ on tan. Iyẹn ni pe o ni ọjọkọjọ ninu oṣu AUGUST, OṢU OWORE ki adajọ ki o to ṣe idajọ yi.

## Iyaafin Mada

(O bẹrẹ loju ewe kinni)

me ni ijẹta gẹgẹbi aṣoju wọn fun ade ojiṣẹ Ọlọrun ti nwọn fẹ gbe iun POPE PAUL Kẹfa tuntun ti nwọn yio ṣe isin fun lọla Sunday ninu ile isin St Paul ni ilu awọn PAPA MIMỌ.

Awọn ara ilu India ti bẹrẹsi kọ awọn agbẹ ilu Dahomey ni ọna bi nwọn ti ṣe ngbin irẹsi (rice) ni oko wọn ni ilu Irome. Awọn agbẹ ilu Ajaṣẹ paapa ti nṣe ipade lati jiroro lori awọn kokoro ti o nje nkan ọgbin wọn loko.

# Alikali Ju Olori Egbe Oselu Kano Sewon

KANO—Gbogbo awọn ti nwọn wa si Kotu ni nwọn pa lọlọ ni ijẹta nigbati adajọ Alkali Kotu Kano sọ Mallam Bello Abdulkadir, Olori ẹgbẹ oṣelu tuntun ti awọn Hausa ṣẹṣẹ da silẹ ti orukọ rẹ nje Ẹgbẹ oṣelu ara Kano (Kano People's Party) ọdun meji; o tun ni ki awọn ọmọ ẹhin rẹ mẹta, awọn, Alhaji Uba, Mallam Gidado ati Malam Isa si ẹwọn ọdun kan abọ ẹnikọkan nitori ẹbi ti awọn ọlọpa ni nwọn mbu awọn oṣelu ti kọ si ninu ẹgbẹ wọn kiri.

Awọn ọlọpa ni lọjọ kọkanla oṣu yi, awọn ọdaran yi ko awọn ọmọlẹhin wọn jade nwọn bẹrẹsi kọrin-ẹbu kakiri arin ilu, nwọn mbu awọn oloye ati awọn agbalagba ilu kakiri. Awọn ọlọpa ni iru iwa bayi le da ruke-rudo silẹ pẹlu ija igboro.

Awọn ọdaran na ni irọ ni awọn ti o sọ wipe awọn ọmọ ẹgbẹ awọn mbu awọn pa mọ awọn; nwọn ni ipade wọrọ ni awọn ṣe. Nwọn ni ẹgbẹ oṣelu tuntun ti awọn ṣẹṣẹ dasilẹ ni nrun awọn ọta ọwọn ninu.

Awọn ọdaran na ni awọn fẹ gbe ẹjọ ti Alikali na da fun awọn lọ si Kotu Kotemilọrun, ṣugbọn awọn ọlọpa ko gba iduro wọn.

# Tiger Elese

**(O bere loju ewe kefa)**

Awọn Oyinbo na ni bi o ba tun jẹ wipe nwọn yio fi ọjọ ija na siwaju ni ẹkan si, a jẹ wipe awọn yio jẹki ẹnikan ti nwọn npe ni Lazio Papp ara Hungari ba Tiger ja ija na ni ẹkunrẹrẹ.

A gbọ wipe lọjọ ti Tiger baja ija rẹ ni Minisita alamojuto awọn oṣiṣẹ, Ọgbẹni J.M. Johnson paapa yio ja ẹṣẹ tirẹ lori apoti kanna ti nwọn yio fi ja ija ni Ibadan, o ni ẹlẹẹ gba ilu Ghana, Jack Toller ni on a ba ja lọjọ na. Iran a dun wo, ipọn a ran.

## E Ka Oro Ilorin Loju ewe Kinni ati oju Ewe Keji

# Eleti—Ofe Daraba

Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosọkọ Street, Lagos, Box 467 Phone 23370; Edito.: (Olotu) Ọla. Ọnatade, 15,Kosọkọ Street, Lagos.